# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 859 LAGOS SARTUDAY MARCH 2nd—MARCH 8th 1963 KỌBỌ MEJI (2)


**Awon Merin Jaja Bo Ninu:**

# Idajo Lori Oro A w o l o w o Ati Awon Omo Eyin Re

EKO —Kotu— ganran ni ọdan l'Eko kun ni ana o fẹrẹ kun a-kun ya fun ogunlọgọ awọn enia ti nwọn lọ si Kotu na lati gbọ gbogbo a-sọ-jare ti ọkan ninu awọn agbẹjọro Ijọba, Ọgbẹni B Kaseem fẹ sọ lori ọrọ ti awọn lọya awọn enia marundinlọgbọn ti awọn ọlọpa nba ro ẹjọ wipe nwọn fẹ ditẹ lati bi Ijọba lulẹ.

Ṣugbọn gbara ti nwọn ti de ibẹ ni adajọ-agba na, Ọgbẹni Geoge S Ṣowẹmimọ, tun sọ fun agbẹjọro ọba na wipe ki o ma ba ọrọ lọ lori awọn arufin na, dipo eyi nṣe ni Ọgbẹni Kaseem sọ fun adajọ na wipe awọn merin kan wa ninu awọn arufin marundinlọgbọn na ti awọn ọlọpa ko fẹ ba ro ẹjọ mọ nitoripe nwọn ko ri ẹri to fun ẹsun wọn, awọn merin na ni Dokita Chike Obi, Olori awọn ẹgbẹ oṣelu ti nwọn npe orukọ wọn ni Dynamic Party, Ọgbẹni Alfred Rewane, tiṣe akọwe oṣelu fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Ọgbẹni Tunde Amuwo ati M. Badmus.

Gbara ti agbejọro Ọba na ti sọ eyi tan ni adajọ paapa ba tẹnu bọrọ, o ni on ko ri idi na ti on tun ni lati ma da awọn ọkunrin na duro si itimọle mọ nitori na ki olukuluku wọn ma lọ si ile wọn.

Bi nwọn ti kuro ninu apoti ile ẹjọ ti n w ọ n bọ si ita ni awọn enia ti o pejọ sita ba gbe gbogbo wọn ru ti nwọn nyọ kakiri Kotu O di ọjọ Jimọ ijọ meje ki nwọn to ma ba ẹjọ awọn yoku lọ.

# Awon Omo'lewe Miran Tun Ba Ijoba Ilorin Soro

ILORIN — Awọn ọdọmọde akẹkọ ti ilu Ekiti ni a gbọ wipe awọn na t u n f i iwe-ẹbẹ kan ranṣẹ si awọn Ijọba ibilẹ Ilorin ati ti Ipinlẹ Ariwa ni Kaduna wipe ki nwọn jọwọ ki nwọn rọ o r ọ ipinlẹ ti a w ọ n alagba awọn ti ntẹnu mọ ṣe, ki n w ọ n pin ipinlẹ na fun awọn ara Ekiti, Obolo, Ọffa ati Igbomina ki nwọn le ribi mojuto ilọsiwaju awọn ilu nwọnyi.

Awọn ẹgbẹ ọdọmọde a k ẹ k ọ na ṣe ipinnu yi ni agbegbe kan ti nwọn npe ni Oke-Opin nigbati nwọn nṣe ipade ajọdun kẹfa ti gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn wa ni idalẹ pesẹ sibẹ.

Nwọn tun pinnu lati kọ iwe-ẹbẹ kan si Minita alamojuto nkan ọgbin ni Kaduna wipe ko si iṣẹ rara fun awọn ọmọ ilewe ẹgbẹ awọn ti nwọn ṣeṣẹ njade ni ile-iwe nitorina ki nwọn da oko-ọba silẹ nibi ti awọn ti o ba ti njade ile iwe a le ma kọ iṣẹ agbẹ ṣe o

Nkan ti o tun jẹ olori ninu nkan ti nwọn ni awọn fẹ ki Ijọba Apapọṣe l'Eko ṣe fun ilu awọn ni ti ọna mọto ti o ti Ajaṣẹ lọ si Kabba; nwọn ni awọn fẹ ki nwọn ba awọn kun u ni lọda. Ninu ipade na ni nwọn ti yan awọn oloye tuntun.

## Odun Itunu Awe Dun L'Eko

EKO — Ọdun itunu Awẹ ti awọn Imale ṣe kakiri gbogbo agbaiye lọjọ Aje (Monday) ni ijẹfa dun pupọ l'Eko, Abẹokuta Ibadan Ijẹbu-Ode ati ilu Kano.

Ni alẹ ọjọ Aiku (Sunday) ti o jẹ alẹ aisun ọdun na ni olukuluku awọn ọlọdun na ti bẹrẹsi yọ ayọ ti nwọn si nṣe adura wipe awọn dupẹ lọwọ Ọlọrun ti awọn ri ipari Awẹ-gbigba na, ọpọlọpọ awọn onilu si nyi ojule kakiri lati fi ilu wọn na da awọn enia na lara ya.

(Wo yoku loju ewe keji)

**Agbako Ori Ede:**

# Malu Pa Aboyun Kan Lona Oja

IBADAN —Adura atata ni adura ti awọn agbalagba ma ngba wipe Ọlọrun majẹ ki a rin lọjọ ti ebi npa ọna. Ob nrin aboyun kan ni akọwe oniwe irohin wa tẹ waya si wa ni ana wipe malu kan ja lọwọ awọn alapata o si kan an pa lọna Inalende.

Alaye ti a gbọ npa jamba iku obinrin na ni pe aboyun ni ṣugbọn amodi fẹrẹ kan nṣe ọmọ rẹ ti o loyun le, iyẹn ni o mu lati mura wipe on a nlọ si ọja Mọkọla lati lọ ra nkan ti on yio a s'agbo fun un.

Nwọn ni bi obinrin na ti nlọ ni ọna ni o pade agbako malu buruku na ti o ja lọwọ awọn alapata ti nwọn nmu lọ si odo-ẹran lati Agọ-Ilọrin, o si bẹrẹ si kan obinrin aboyun na ni iwo titi ti o fi paa de ọrun.

Awọn Ọlọpa si nṣe iwadi kilo fa iru jamba yi lọwọ di bi a ti nkọ irohin yi.

# Awon Oselu Togo Faake Kori

LOME—Awon ọmọ ẹgbẹ oselu ti Ologbe Dokita Olympio, alakoso ilu na ti nwọn lu pa ni aipẹ yi ti fi aake kori wipe awọn ko ba enikan ṣe ipade lori ọrọ ilu Togo a fi ti awọn soja olote ti o ko awọn eni wọn lọ pam si ọ ba awọn da wọn silẹ patapata.

Ninu ọsẹ yi ni Ọgbeni Nicholas Grunitzky fi iwe ranṣẹ si gbogbo awọn ẹgbẹ oselu ati ṣoja ilu rẹ wipe ki nwọn wa ba on ṣe ipade lati jiroro lori bi awọn yio ṣe ṣe ti idibo si.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Olympio ti nwọn npe orukọ wọn ni Comite de L'Unite Tog lati ṣeni iru ipade wo ni nwọn ni ki awọn wa ba wọni nigbati o jẹ wipe gbogbo awọn olori ẹgbẹ awọn nQnwọn ti tuka, Ọkan ninu awọn Minisita awọn ri, wgbeni Theo Mally ti lọ sa pamọ ni ilẹ Nigeria; n on tilẹ tẹ waya si wipe ki o wa si ile sugbon o kọjalẹ.

Ilu Eko ni Ọgbeni Mally na fi ijoko rẹ si ni Nigeria.

Nwọn ti bẹrẹ ipade wọn na ni Lomẹ ni ijẹrin, Ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn wa sibẹ lati wo iran ni nwọn ko fun laye rara nitoripe titi ni nwọn ti ilẹkun ibiti nwọn gbe nṣe ipade na.

Onirohin wa ni on gbọ wipe nwọn nṣe eto lati yi ofin idibo ilu na pada si eyi ti gbogbo awọn ara ilu na fẹ.

# Odun Itunu Awe Dun

## (0 bere loju ewe kinni)

Ni owurọ ọdun gaan, ọpọlọpọ awọn Musulumi na wa bẹrẹsi fi ebun idupẹ ti nwọn npe ni "JAKA" ranṣẹ si awọn lemomu ati alufa Mọsalasi wọn kakiri.

Ni Eko agogo mẹwa owurọ ni awọn janma ilu fi asiko atikirun si, ki o to to asiko na gbogbo ẹsẹ awọn janma na ti pe si Ọbalende lọmọde lagba pẹlu awọn Oyinbo ti nwọn jẹ Imale paapa ti nwọn wa kirun.

Bi agogo mẹwa ti de oju rẹ bayi ni Ọba Adeniji Adele Keji yọ pẹlu gbogbo awọn oloye rẹ, awọn bi Oloye Onisẹmọ, Onisiwo, Oluwa, Eletu Iwasẹ ati Balogun ilu, Arẹ ilu pẹlu Asiwaju ilu.

Lemomu gbogbo ilu ni o ṣe eto isin irun na, ko si si ija ati gbolohun asọ ni ibẹ, gbogbo nkan si lọ dede. Bi nwọn ti ki irun tan ni Ọba Adele bẹrẹsi ba awọn awọn ara ilu sọrọ; Ọba na ki gbogbo wọn ku ọdun. O ni enikẹni ti o ba ṣe akiyesi a ri wipe awọn ọmọ ode isisiyi ko fẹ mọ nkan ti nwọn npe ni iwa-rere mọ.

Ọba Adele ni ti a ba nfẹ ilọsiwaju ilu wa, iwarere ni o yẹ ki a ma hu ni ipo ki po ti a ba wa. Ọba ni a bi ni l'Eko ko d'ọla rara iwa-rere ni ẹsọ enia.

Lẹhin ti Ọba ti ki wọn ku ọdun tan ni olukuluku ba mura ti nwọn gba ọna ile wọn ti nwọn bẹrẹsi jo ijo-ayọ.

Gbogbo awọn ara ilu lọkunrin ati lobinrin ti nwọn fẹ ri bi eyẹ ojo na ti ri ni nwọn wa to si oju ọna Gbamgbose, ita Tinubu ati Ehin-ogba lati woran awọn Imale ti nwọn ndari bọ Mọsala-Idi.

NI ABẸOKUTA, ẹsẹ gbogbo awọn Imale ni o kun siba-siba si Lantoro leti Adatan nibiti nwọn gbe ti nkirun. Lẹhin eyi gbogbo wọn jo gba ojude Alake lọ.

A ti irohin gba wipe Ọdun Awẹ na dun, o si larinrin ni Kano, Zaria ati Ibadan.

CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT:
IKORODU TRADING GOMPANY
20 & 28 Balogun Street, Lagos.

Plushes, Velvet, Velveteen, Damask & Building Materials

PLEASE CONSULT

Okunowo Brothers

63, Massey Street, (Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

Eleti-Ofe D'araba

### "Olofintoto" Eleti-Ofe Fi Oju-agba Wo

# Iwe Ti Iya Ajagbe Ko Lati Ilorin....

Ninu iwe itan mi lọsẹ ti o kọja mo sọ nipa bi nwọn tiṣe mu awọn ara ilu-Oke wọ iṣẹ a-ngbaru nidi ọkọ elefin l'Eko ati Apapa lẹhinti awọn Kurumọ fi ọpọlọpọ ọdun ṣe iṣẹ na laisi wahala kan. Ṣugbọn ki nto ma ba itan mi na lọ lori awọn oṣiṣẹ ọkọ ti nwọn da iṣẹ silẹ ninu oṣu ti o kọja yi ma fẹ ki ẹnyin ọkawe mi ka iwe "wosika" kan ti Iya kan lati Ilọrin kọ sọmọ rẹ l'Eko. Iwe wosika na niyi:

"Ajagbe mi ọ w ọ n, ṣe alafia ni o wa ati iyawo rẹ Belawu ? ọrọ ti mo gbọ lana lati ọdọ a w ọ n ero Eko kan ti nwọn de si ile awọn burọda mi ni O k e Pakata jẹ kayefi fun mi. Nwọn ni gbogbo a w ọ n ọma Oke Ọdẹ, Ilọrin ati awọn ara Ganmọ ti nwọn nṣe iṣẹ Oloyinbo ni nwọn ti binu da iṣẹ silẹ.

"Walai talai, n k'o tete gba ọrọ na gbọ rara a fi gbati mo de ile ọkọ ẹgbọn Belawu ti o wa ni Onitaniganran ti nwọn ni ki ntete kọwe si ọ ki o mọ ba wọn ṣere a nda iṣẹ silẹ rara.

"Jọwọ Ajagbe, ko si iṣẹ ti ọdọmọde kunrin le ri iṣe ni Ilọrin nisisiyi; ti ile iṣẹ iṣana ti awọn Ijọba ṣe dasilẹ, awọn enia ti nwọn fẹ wọ ibi iṣẹ na ti pọ ju iṣẹ paapa lọ. Nwọn ni nwọn tun fẹ da iṣẹ ... Oyinbo silẹ ni ... Saadu.

"Ṣe iwọ na mọ igbati o ti wa lẹnu iṣẹ Apapa na, abọ akara san ju ki enia mọ ri akara jẹ rara lọ. Ẹ ku iṣẹ lada ti Awẹ. Ti o ba ri ero ti nwọn mbọ wa si Ilọrin ki o ba mi ra iru panu abọmọfọ ti o fi ran Mọrinade s i m i n i ijosi ki nri nkan ma fi kọ oka tuo si.

"Too, ọrọ mi ko ju eyi lọ.

Emi ni iya rẹ,
Asimọwu Amọpe."

Ẹnyin ọ k a w e mi, ṣe ẹnyin na ri ọ r ọ iya lara ọmọ bayi ? Iyoku di i n u osẹ ti mbọ ki nto bọ aṣọ-awọn loju egungun lori ọrọ awọn ti o da iṣẹ silẹ na.

Ẹyin ọkawe mi ti ẹ mba Ologbe Biney ṣiṣẹ l'Apapa, ẹ ku aṣẹhinde ti Ọ g b ẹ n i Biney na ti o jalasi ni ọsẹ ti o kọja.

### Kini Ti wa Ti Je

# Awa Omo Igbomina Ofa Ati Ekiti?

Mo ki gbogbo ẹnyin ọmọ ilẹ Igbomina, Ọffa, Ekiti ati Odo-Oogun ti o wa ni Naijiria, Ẹ ku ọrọ ilu wa ilẹ Igbomina, ominira ti anja fun, Oluwa yio jẹ ko tẹ wa lọwọ ni kiakia, mo ki gbogbo ẹnyin agbagba ilẹ Igbomina ati Ọffa ti o fi de Akiti a t i Odo-Oogun, wahala nyin Oluwa yio jẹ ko yọri si rere laipẹ yi jọjọ.

## Lati Owo Edatomolakosi

Bakanna nko le gbagbe Ọgbẹni wa M. A. Ọdẹkunle ti o ti bẹrẹ si kọ iwe jade lati nkan bi ọdun meji sẹhin nigba ti Divison bi o tilẹ jẹ pe o ni ọpọlọpọ alatako nipa ti Division yi, gbogbo awọn ti ki ye nigbana gbogbo wọn lo ronu piwada ti nwọn si gba tirẹ nisisiyi, nitorina mo dupẹ lọwọ Ọgbẹni Ọdẹkunle, oye ati lakaye ti Ọlọrun fun un ki Ọlọrun ma ṣe gba a, ko si ma ṣe igbega fun ninu iṣe rẹ.

Mo bere mo ni kini ti awa Igbomina yio ti jẹ ohun to mu mi bere ibere yi nipe, ọrọ nipa ti ipade Ajaṣṣẹ'po ti nwọn ni ka yan e n i a mejilelogun w a ti nwọn yio ma ṣeto ilẹ wa,. Iru enia ti o yẹ tobi ti a ro pe o yẹ ko wa ni ipade na, ao gbọ pe nwọn yan wọn sinu ipade na, ti nwọn yio fi ma sọrọ Division dada, awọn na ni bi Ọgbẹni P. B. Ọlatunde, J.G. Ẹkunrin, M. A. Ọdẹkunle a t i awọn ti ọkan nwọn ngbona si ọrọ Division awọn ni o yẹ ti a si ro pe ki nwọn wa ni ipade na.

Ọrọ na ko yen dada, nitorina yio w u mi, k i Ọgbẹni M. A. Ọdẹkunle tiṣe akọwe Igbomi Parapọ le ṣe alaye na fun gbogbo wa ni ẹkunrẹrẹ' nitori a ko ni fẹ awọn ti ko f ẹ mọ sọrọ Division ninu ipade n a rara nigbati a ba ko awọn ti ko fẹ Division si bẹ ko ni boju mu, nitorina ẹnyin agbagba ilẹ Igbomina dọwọ nyin kẹ parapọ ki ẹ tubọ ṣe etọ ilẹ wa na daradara ki gbogbo ilẹ wa le dọgba, ki ohun gbogbo wa si ṣẹ deede.

Lakotan, a ngbọ gbogbo wahala ti ẹ ... ṣe, paapa ipara nyin lọ si Kaduna ni gbogbo igba, ṣugbọn ao mọ kini ababọ nipa ti Division ilẹ Igbomina o yẹ ki a mọ ibi ti o nlọ, ati iru ipo ti ilẹ Igbomina wa ni akoko yi. Emi na ri ka ninu iwe Irohin "Eleti-Ọfẹ' pe ọrọ Igbomina ati Ilọrin gba suru bi o tilẹ jẹ pe Ogbẹni Ọdẹkunle fesi ọrọ na, ṣugbọn sibẹ sibẹ a ko ti mọ ipo ti awa Igbomina wa ri wakati yi. Ẹ la ọrọ naiye wa yekeyeke. Kinini tiwa yio ti jẹ?



ELETI-OFE

A NIUWON KO SE WI LEJO

EDITORAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos, P. O. Box 467 "ELETI—OFE" LAGOS Phone 23370

VOL XIV. NO. 858 SATURDAY MAR. 2nd— MARCH 8 1963

# Imale Ki Jo Bata

NI ALAIṢE iyemeji a ṣe akiyesi wipe gbogbo ẹnyin ọkawe wa ni ẹ ka irohin kan ti AYILUKA ile irohin Eleti-Ọfẹ tẹ jade ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi wipe awọn baba wa. Musulumi Eko tun fẹ fa ọtẹ gbi-gbona kan yọ lori ile isin wọn. Mọṣalaṣi Jimọ ti Ẹhin-ọgba. Ọtẹ na si dabi eyiti awọn kan ṣe ni iwọn ogoji ọdun sẹhin ti Lọya agbẹjọro ni Kotu kan fi sọ orukọ ọtẹ igba na ni "Imale ta ju Koko (cocoa) lọ" nitoripe o ri wọn rẹ jẹ dada lori ọtẹ na nigbana.

AWỌN YORUBA pa a l'owe wipe ẹniti oriṣa Ṣango ba toju rẹ wọlẹ ko ni bu Ọba Koso mọ lailai. Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ti gbọ ọpọlọpọ ọrọ nipa edeaiyede ti o bẹ sılẹ larin awọn Musulumi Eko ri a, ṣugbọn nigbati a gbe ọrọ awọn janma mejeji ti nwọn fẹ fi ija bẹ ẹ yi yẹwo, a ri wipe ọrọ na ko to eyiti a le ma f'apa janu si. Ọrọ na ko ju nsa ti awọn tọtun tosi le joko si ki nwọn si pe awọn "ỌMỌ KEWU" ki nwọn ba wọn dasi lọ. Ọrọ na koto eyiti a le fa ara wa lọwọ ni tẹtẹ lọ si Kotu-ganran niwaju awọn alabẹ ṣekele si.

Ni idakeji, ina wa si tun dun lati gbọ wipe awọn agbalagba ilu Eko ti dide si ọrọ na lati ba wọn pana ọtẹ na. Nitotọ ni nwọn sọ wipe agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ tuntun ko pa.

A bẹ ẹnyin Oloye wa, Ọba Adele, Balogun gbogbo ilu (Alhaji A. Y. Ojikutu), gbogbo ẹnyin Lemọmu adugbo kọkan pẹlu awọn Iya-adinni Mọṣalaṣi ti mbẹ l'Eko, ki ẹ jọwọ ki ẹ bawa pari ọrọ na fun awọn Musulumi ti nwọn nja lori ọrọ Mọṣalaṣi Jimọ nitoripe Imale ki jo bata, Ọba ko f'ori ji ni. 3.1.5



Ogbeni Akowe Adajo ti ilu Oyinbo niyi

# Iwe Si Olotu

## Yoruba Atata Ni Ti Atilade

Awọn Yoruba ni bi ọmọ ẹni bi 'dara ki a wi a ko kuku ni fi ṣe aya, iyẹn ni ọrọ kan to jade laipẹ yi ninu iwe Eleti-Ọfẹ lori awọn iwe a-kọ-ni-lede Yoruba ti Alufa (Rev) E. A. Atilade ṣe fun awọn ọmọ ile-ẹkọ ilẹ wa ti Alhaji Disu sọ nipa bi awọn iwe na ti kọ enia lọgbọn to.

Ọlotu, emi na ti fẹ sọrọ nipa awọn iwe Alufa Atilade yi ti pẹ, ṣugbọn Alhaji Disu ti ta mi yọ. Ki a si sọ ti otitọ, Yoruba atata ni o wa ninu awọn iwe na.

Emi alara paapa si nma ngba awọn ọrẹ mi ti nwọn ba wipe wipe ede Yoruba nma wu awọn lati ka sugbọn o ma nnira fun awọn, wipe ki nwọn lọ ma ka iwe Yoruba ti Atilade. O kọ enia lede ati ọgbọn.

Emi ni,
Tiṣa Olukọni

Ita Ẹlẹwa,
Ikorodu

## Mo Gba Fun "Olofintoto"

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe yin Eleti Ọfẹ lati kan sara si onirohin yin ti o njẹ "Olofintoto" fun gbogbo alaye itan ti o kọ nipa ọrọ ilu Togo ati bi Dokita Olympio alakoso ilu na ṣe ku.

Emi ti o tilẹ jẹ wipe eti Togo ni mo ngbe lati igba ọmọde mi, nkọ mọ itan awọn oṣelu na tc bi ọgbẹni Olofintoto yi ṣe pa itan na. Gbogbo awa ti a ka Eleti-Ọfẹ ni ilu yi ni a gbadun rẹ.

Ẹ jọwọ ki e ma ba wa tẹ itan orisirisi sinu iwe yin na ki a le mọ ni ọgbọn si iwaju si.

Emi ni,
S. Akanbi

Porto-Novo,
Dahomey



## Fila Dide Ni Mosalasi

Ẹ jọwọ boya a le ri ẹniti o le la ọrọ yi yemi daradara ninu awọn ọkawe nyin. Mo fẹ mọ kiloṣe ti awọn ẹlẹsin Imale fi mọ nde fila wọn wọ ile ti nwọn nsin Ọlọrun ti nwọn npe ni Mosalasi.

Mo ṣe akiyesi wipe gbogbo wọn ati Alufa Lemọmu ti o nṣaju wọn ni nwọn ma mbọ bata ẹsẹ wọn silẹ ki nwọn to wọ Mosalasi lọ. Kinni o wa fa ti fila dide ni iwaju Ọlọrun? Awa Onigbagbọ ka iru iwa bayi si afojudi.

Ẹ jọwọ, ẹ la ọrọ na ye mi.

Emi ni,
Samson Ọjẹtunde

Alagbado.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## ( Lati Owo Ayiluka )

### GBO TOKO

Iwe ti ma kọ kọ niyi lẹhin igbati a ti ṣe ọdun itunu Awẹ tan, o si yẹ ki nki ẹnyin ọrẹ mi lọkunrin lobinrin ti ẹ niran mi, ti ẹ fi JAKA ransẹ si mi. Ẹ ṣe pupọ ọdun na yio yabọ fun gbogbo wa. Ẹniti o ba ni ọmọ nile a ri owo fi tọ ọ, ẹniti ko ba ti ni Ọlọrun a gbọ adura rẹ, ẹniti o ba loyun a bi tibi tire, gbogbo wa ko ni ku iku ojiji.

### GBOT'AYA

Ọdun ọdun ni dun pupọ ju (a ko gbọdọ wi nkan miran), gbogbo awọn iyawo ti o gbọran sọkọ wọn lẹnu ni ọkọ wọn ra asọ "GBỌ-TỌKỌ" fun, gbogbo awọn ọkunrin ti nwọn si ngba ọrọ iyawo wọn ni awọn iyawo wọn ra asọ fila "GBỌ-TAYA" fun. Ẹnikan ninu wọn tilẹ pe mi si ibi ase kan ti o ṣe fun awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ni Suru-Lere.

Nibẹ ni mo ti gbọ orukọ awọn asọ na ati wipe ko si owo lode, nṣe ni olukuluku nyi ikan mọ ikan.

### Balogun Eko

Mo ro wipe ọpọlọpọ ẹnyin ọkawe mi ti ẹ wa l'Eko lọ wo iran awọn Imale ọlọdun ni iṣẹfa nigbati nwọn nlọ kirun ni Mosasi Idi ni Ikoyi ati igbati nwọn npada bọ l'Ẹhin-Ọgba l'Eko. Njẹ ẹ kiyesi Oloye ti o wọ asọ gẹgẹbi awọn Oyinbo olori awọn jagunjagun ? Balogun gb gbo l E ... Iyẹn nikan kọ, mo gbọ wipe Oloye (Alhaji Abubakr Yẹkinni Ojikutu) tun jẹ Balogun fun gbogbo awọn Imale Eko Balogun tirẹ di pupọ.

Ẹjọwọ Oloye Ojikutu, tani telọ adasọ ti o ba nyin da asọ na tabi lati ilu Oyinbo ni nwọn gbe ti ba yin da a wa? Ẹjọwọ nko fi ṣe afojudi, mo ni Ọgbẹni kan ti nwọn ṣẹṣẹ fi jẹ Oye Balogun lọna ilu wa, o si ṣẹṣẹ gba owo koko (cocoa) jaburata lọdọ awọn Oyinbo ni, boya yio le ra ẹṣọ iru iyia bayi nitoripe a-lowo-ma-tanna ni orukọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ npe.

### Baba Ni Baba

Ki a mọ pupọ Ọba wa, Adele ... ri wipe ẹniti o yẹ ni on gbe Oye Balogun Eko fun eyi si jẹ ki nni ... Gbadamọsi Macgregor olori awọn ọmọ ẹgbẹ Killa ni Abẹokuta nigba aiye ... bi o ti nwọ aṣọ ti nwọn ba lọ si Mọsalasi ọdun Baba ni baba njẹ ! Ki ẹ jọwọ ki ẹ ba mi ki Ọgbẹni Makanju ọrẹ yin. Ẹsọ na yẹ yin pupọ o!

### Oni-Bara

Laipẹ yi ni emi Ayiluka sọ nipa ofin kan ti nwọn fi de awọn onibara mọlẹ ni ilu Kano ati pe ki Olotu Ijọba wa Ọlọla Tafawa Balewa ki o jọwọ ba wa ro ti awọn onibara ti ilu Eko yi ṣe nitori pe nwọn pọ pupọju.

O ya mi lẹnu nigbati mo ri moto awọn ọlọpa ni ijẹjọ ti nwọn bẹrẹsi ko awọn Hausa onibara na sinu moto ra. Nibi ... nwọn nko wọn gbe ni ko ye mi si rara. Ọrẹ mi kan ... bi nwọn fẹ ko wọn lọ si ilu wọn ki nwọn ba le ka wọn mọ awọn ... ti nwọn fẹ tun ka (census) ni. Ki a s mọ wo na.

( Wo iyoku loju ewe kejọ )



"ẸI IWỌ BA NWÁ ... FUNRA RẸ"



Gbogbo awọn to wà ninu moto



...ọ ha nwá asiki funra rẹ bi?

...i yio pẹ lọ titi fun ọ bi o ba nfi owo pamọ

...tigba dẽgba nile ipamọ owo ti Barclays

Owo rẹ mbẹ labẹ abo Ìgaṣọ Barclays. Ki yio sọnu atipe bi o ti npọ nibẹ si bẹni yio ma lési. Lọ bère nibiṣẹ Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo pamọ ki o si bẹrẹ lati ṣe bẹ ni kiakia.

BARCLAYS BANK D.C.O.

# Awon Ara Togo Fe Se Ipade Idibo

## Maga Sare Wa Si Nigeria

LOME— Ijangban ko ṣe nikan fa! Akọwe Onirohin wa fi waya kan ranṣẹ si wa lana wipe Ọgbẹni Nicolas Grunitzky, ti awọn ọlọtẹ ṣọja ti nwọn pa Ologbe Olympio̤pe wipe ki o wa ṣe Alakoso Ijọba ilẹ Togo ti fi aake kọri wipe on ko ni le ma ba eto akoso Ijọba na lọ mọ b nwọn ko ba jẹ ki awọn pejọ lati jiroro lori idibo.

Mo gbọ wipẹ alakoso Ijọba tuntun na ti fi iwe ranṣẹ si gbogbo awọn ẹgbẹ oṣelu ilu na, ti o fi de ọdọ awọn ọmọ ẹgbe alatako ti Ologbe Olympio wipe ki nwọn wa ba on ro bi awọn yio ti ṣe ọrọ idibo si.

Ọgbẹni Grunitzky ni on fẹ ki awọn ara ilu on TETE dibo lati yan ẹniti nwọn ba fẹ ki o ṣe alakoso Ijọba tuntun ki gbogbo Ijọba agbaiye ilu Afrika to ṣe ipade nla ni ilu Addis Ababa ni Itopia.

Ni irọlẹ ijẹjọ, Alakoso ilu Dahomey sare wa si Nigeria lati ba Olotu ilẹ na sọrọ ni aṣiri ni Ikẹja k i o to tun sare wọ ọkọ aropileni pada si Contonou lẹsẹkanna.

Ko si ẹniti o mọ nkan ti awọn oṣelu mejeji sọ, ṣugbọn awọn enia kan ni o da awọn loju wipe nwọn fẹnu kan ọrọ ilu Togo ti ẹnu awọn ara ilu na ko ti ko ẹnu lati igbati nwọn ti pa Dokita Olympio.

# Obinrin Agbaworan



**Aworan yi ni ti Omidan Camilla Jessel, omo odun medogbon ti o n g b a aworan kakiri agbaiye ti o fi de ilu Afirika fun ise anu lati fi wa owo fun ise igbala awon omo owo. Omidan na ti rin egbarun ibuso ti o nya a w o n aworan na kiri.**


## Nigerian Ports Authority

INVITATION TO TENDER

SALE OF FEROUS MATERIALS — PORTHACOURT

SIX — MONTHLY

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period up to and including 30th June 1963, in the Authority's Dockyard and Quays at Port-Harcourt or any other particular point where the Authority may have scrap materials for disposal in the Port Harcourt area.

2. A copy of the Tender Form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, and the Port Manager, Eastern Ports, Port-Hacourt, on payment of a deposit of £5 to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays, Lagos, and the Area Accountant, Port Harcourt Quays. The completed Tender Form should thereafter be returned to the Secretary, irrespective of where the form has been obtained, in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL - TENDER FOR SCRAP" so as to reach him not later than Tuesday, March 12th 1963.

3. The deposit of £5 will not be refunded in any event to any tenderer, who, upon being advised of the acceptance of his tender, fails to pay for and to remove the materials made available.

4. Tenderers are warned that scrap available for disposal may comprise both ferrous and non-ferrous materials although it is expected that most of the materials will be ferrous.

5. During the period indicated above, the successful tenderer will be required to remove, at his own expense, whatever scrap si made available for sale (with the exception mentiond above) within 7 days of being notified to do so. He will also be required to make necessary arrangements at his own expense for all such scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority befo e being removed.

6. The Authority reserves the right to resell any materials not removed by the purchaser after 7 days of payment of purchase price, and such purchaser shall forfeit such payment in the event of such non-removal.

7. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice. NO. 858.
20th February 1963.

# Moslems In Britain Celebrate Eid-el-fitr

LONDON — Moslems throughout Britain have been celebrating the end of Ramadan in traditional fashion.

Over 1,500, including many West Africans, gathe red at the Shah Jehan Mosque at Woking in Surrey to join in prayers and to share a meal of saffron rice and curry.

This was eaten in large marquee which had been draped with the national flags of all the countries represented, and floored with hay supplied by British farmers to keep out the winter cold.

Many more West Africans were among the 2,000 who celebrated the Eid-El-Fitr at the Islamic Cultural Centre in London, where luncheon was followed by national songs.

Similar celebrations took place in mosques all over Britain.

## New Cargo Ship For Nigeria

LONDON — The second British-built ship for the Nigerian National Line Ltd. the "Amodu Bello," will be launched on the River Tyne, in north-east England, on 12th March.

The new ship, a cargo liner of 9,500 tons, is similar in construction to the "Nnamdi Azikiwe," which was handed over to the owners in January on successfull completion of her trials. Like its predecessor it was built in the Wallsend-on - Tyne shipyards of Swan, Hunter and Wigham Richardson.

Chief Kolawole Balogun, Chairman of the Nigerian National Line Ltd., is expected to be present at the launching. The naming ceremony will be performed by Mrs. R A. Njoku, wife of the Federal Minister of Transport and Aviation.

---

LARGEST IN THE WORLD:

## Britain's Chocolate Industry

LONDON— Britain's chocolate and sugar confectionery industry is one of the largest in the World and an important customer of Commonwealth agriculture, says the London "Financial Times" of yesterday in a special page devoted to the "steady home and export demand" of this industry which employs over 100,000 people in Britain.

Furthermore, the British had become the largest consumers of confectionery in the world, buying 600 tons a year or an average of over eight ounces per head per week.

In recent years the sales of chocolate had increased significatly and outstripped those of other types of confectionery, said the "Financial Times".

Also, the industry was far and away the largest exporter of coco, chocolate and confectionery in the world, shipping overseas an average of 1,000 ons of sweets every week - four times the pre - war average.

Nor was the industry resting on its laurels. It was using every effort to increase trade, thereby using more and more Commonwealth cocoa, sugar, paper and packaging materials aluminium foil and cellulose film.

## Britain Enters Gas_turbine Car For Road Race

LONDON—Britain will be the first country to have a gas turbine car in an inter national road race, when world motor-racing champion Graham Hill and his B R. M. team mate Richier Ginther drive the British Rover-BRM gas turbine sports car in the Le Mans 24-hour race in June.

The engine of the Rover-BRM develops 140 B.H.P. and has a top speed of 200 m. p. h.

## World-Wide Celebration For Shakespeare's 400th Anniversary

LONDON — The 400th anniversary of Shakespeare's birth will be commemorated at his birthplace, Stratford - upon - Avon, Warwickshire, next year by the opening of a Shakespeare centre in the town and an exhibition of the life and times of the poet. This will be staged on a site bordering the River Avon The Exhibition, which will cost £100,000, will move on ,o Edinburgh and London in August.

The celebrations generally will be on an international scale, Mr. Levi Fox Director and Deputy Chairman of the 1964 Shakespeare Annivesary Council has stated. Commemoration arrangements are also been made in the United States, Canada, Australia, India, Japan, France, Germany and Italy.

The Stratford celebrations will last from April until December.

A season of plays at the Royal Shakespeare Theatre in Stratford will be staged and an international birthday party, musical works and a commemorative service are also planned.

Special displays are being held at places associated with Shakespeare's life at Straford.

---

## At The Press Conference



President Kennedy replies to a question during a press conference at the State Deparimeut auditorium ni Washington, D.C. The President holds frequent meetings with newsmen to inform the people of the United States and the world of current Administration plans and policies.

# Ayiluka

(O ṭẹ̀ ọrọ loju ewe karun)

## Mosalasi Jimo

Irohin kan ti Olotu Eleti-Ọfẹ gbe jade lọsẹ ti o kọja, ti nwọn pe ni ọrọ ọtẹ "IMALE TA JU KO-KO lọ" mu mi niran ọrọ itan pupọ lori Mọṣalaṣi Jimọ ilu Eko nigbati a nlọ si ile-iwe. Ọtẹ na si sọ awọn miran di edun arinlẹ.

Mo gbọ wipe ede aiyede ti o tun fẹ bẹ silẹ larin awọn baba wa Imale yi lori ọrọ Mọṣalaṣi Jimọ yi kanna ko ni lọwọ amodi AIPERI ninu nitoripe awọn agba-lagba kan ti a lepe ni MAJẸ-KO-BAJẸ ni arin awọn janma na ti bẹrẹsi pẹtu si i. Nwọn ni agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ-tuntun ko wọ. Ẹ jọwọ ẹnyin Lemọmu, Balogun ilu ati ẹnyin saraki-saraki ni ilu Eko, ọrọ awọn janmọ di ọwọ yin, ẹ ba wa pari ede aiyede na fun wọn. Allah yio fun yin ṣe o! Emi Ayiluka ko gbagbe ẹyin Ọba ati Oloye wa, ki ẹ jọwọ ki ẹ gba wa o.

## Awon Dereba

Bi ọdun yi ti dun fun awọn ti o nta bata lọja ati awọn alaṣọ ni mo gbọ wipe o dun pupọ fun awọn Dẹrẹba ti o nfi mọto bọlẹkaja ko enia pẹlu awọn baba onikabukabu, bi nwọn ti npawo sapo ni biribiri bẹni awọn ẹlẹgiri ti o wa loju ọna ngba owo na lọwọ wọn. Lọjọ wo ni ọrọ biribiri yio to tan nilẹ yi?

## Enkuari Kano

Ọtẹlẹmuyẹn ọrẹ mi kan fi irohin ranṣẹ si mi lalu Kano wipe iyọri iwadi (enkuari) Oyinbo Mu-t ti o ṣe lori Ijọba ibilẹ ilu Kano lọpẹ yi ti tẹ awọn "babangeri" lọwọ ni Kaduna, nwọn si nro nkan ti nwọn a ṣe lori rẹ. Nitori awọn ti nwọn lu owo Olowo ni ponpo ni nwọn ṣe ṣe iwadi ile iṣẹ na. Ijọb Ipinlẹ Ariwa ni o ya awọn Ijọba Ibile Kano lowo nigba kan ti nwọn fi san owo awọn oṣiṣẹ wọn. o



## Awon Imale Eko Fe Pari Edeaiyede

EKO —A gbọ irohin ni irọlẹ ana wipe ọnọ ede-aiyede kan ti o ti nja ran-yin larin awọn janmọ Mosalasi Jimọh ni awọn agba-lagba kan fi ẹnu kan lẹ-hinti nwọn kirun Janmọ tan ni Mosalasi Jimọ na lana lati pari ọrọ na larin awọn ti nwọn nfẹ ja ija na.



**Comfortable and safe**

A roomy 5–6 seater, space for lots of luggage, luxurious appointment, excellent finish, a very high standard of safety: these and many other welcome features you find in both of the 190 models and besides the 190 Diesel offers quite exceptional economy. Let us demonstrate by a trial run, free of any obligation, what excellent value these cars represent.

MERCEDES-BENZ

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (E.B.) IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT-HARCOURT: ABA

Sub—Distributors:

## ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY: ONITSHA: ABA.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street Lagos Box 46 Phone 23370 Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.